# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ÀJẸ́ ÉDÓRÌ

## Ìtàn ...

**1 Samueli 28:3-25**

Inú Ọba Saulu ti pòpọ̀, kò sí mọ ohun t'o le ṣe mọ́, ó sì wárìrì pẹ̀lú ìbẹ̀rù. Àwọn ologun Filistini ti kó ara wọn jọ lati ba àwọn ọmọ ogun Israeli kékeré àti alailagbara jà. Saulu sọ̀fọ̀, "Bí o bá jẹ́ wípé Samueli wà nihin, ìbá ti ṣọ ohun ti emi yio ṣe fun mi." Sùgbọ́n woli nla Israeli ti kú ni ìwọ́n ọdun díẹ̀ sẹhin.

Ọba Saulu gbìyànjú títí boyá yio ri ìmọ̀ràn gbà lati ọdọ̀ àwọn woli miran tabi awọn alufa, sùgbọ́n Oluwa ko da a lóhùn. Gẹ́gẹ́ bi ọmọdekunrin, Saulu sunmọ̀ Ọlọrun. Sùgbọ́n lẹ́hìn tí ó gun orí ìjọba tán, o di apọ́nilójú àti ọlọ̀tẹ̀ sí ọ̀rọ̀ Ọlọrun. Ó pa gbogbo awọn alufa abúlé kan tán lẹ́ẹ̀kan soso. Ọba Saulu ntẹsíwájú lati má a ṣe àìgbọràn sí Oluwa, níbayi nínú ìrora, Ọlọrun kò sì dá a lohùn.



"Saulu sì wí fún awọn iranṣẹ rẹ̀ pé, Ẹ ba mi wá obinrin kan ti o ni ẹ̀mí abókuṣọ̀rọ̀, emi o si tọ̀ ọ́ lọ, emi o si bèrè lọ́dọ̀ rẹ̀." 1 Samueli 28:7. Ọlọrun ti paṣẹ fun awọn eniyan Rẹ̀ gbangba pé wọn kò gbọdọ̀ lọ sọ́dọ̀ àjẹ́ tabi abokusọ̀rọ̀ (Lefitiku 19:31; 20:27), sùgbọ́n Saulu kò ka aṣẹ Ọlọrun si pàtàkì.

Nígbàtí Saulu tún rí obinrin kan ni Édórì ti o ni ẹ̀mí abokusọrọ, ọba tún pa ara rẹ̀ dà kí ó tó lọ. O wí fún abokusọ̀rọ̀ náà pé, "Mu Samueli gòkè fun mi wá." Àjẹ́ náà sì lọ nínú ọ̀fọ̀ àti ìfàya rẹ̀, títí tí òkú kan fi jade si i, ti ó pe ara rẹ̀ ni woli Samueli, ó sì sọ̀rọ̀ ti kò ni ìrètí fun ọba. O sọ fun Saulu pé, oun ati awọn ọmọkunrin rẹ̀ mẹtẹẹta yio kú ni ọjọ́ keji nínu ogun.

Ni ọjọ́ keji, awọn Filistini pa awọn ọmọkunrin Saulu, lehin ikú awọn ọmọ rẹ, o ti gba ọgbẹ́ ati pé nkan ti sú u, o subú lórí idà ara rẹ̀, o sì gba ẹ̀mí ara rẹ̀ (1 Samueli 31:2-4). Talo ba Saulu sọ̀rọ̀ nipasẹ àjẹ́ - woli Ọlọrun to ji dide tàbí èṣù tó paradà?

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Njẹ́ woli Samueli ni Saulu rí dájúdájú?
   **1 Awon Oba 22:22**
   Oluwa sì wí fun un pé, Bawo? O sì wípé, Emi o jade lọ, emi o sì di __________ li ẹnu gbogbo awọn woli rẹ̀. Oun si wípé, Ìwọ o tàn án, iwọ o sì borí pẹ̀lú: jade lọ, kí o si se bẹ̃.
   **Ifihan 16:14**
   Nitori _________ _________ ni wọn, ti nse iṣẹ-iyanu, awọn ti njade lọ sọdọ awọn ọba gbogbo ilẹ̀ ayé, lati gbá wọn jọ si ogun ọjọ́ nla Ọlọrun Olodumare.

2. Se okú tún ma nbá alàyè sọ̀rọ̀ tabi kí o pa wọn lára bí?
   **Jobu 14:21**
   Awọn ọmọ rẹ̀ bọ sí ipò ọlá, oun ko si ________, nwọn sí rẹ̀ silẹ̀, oun kò sí kiyesi i lara wọn.
   **Oniwaasu 9:5,6,10**
   Nitori alàààyè mọ̀ pe awọn o kú; ṣùgbọ́n awọn okú kò ________ ohun kan, bẹ̃ni nwọn kì ini èrè mọ; nitori iranti wọn ti di ìgbàgbé, _____ wọn pẹlu, ati irira wọn, ati ilara wọn, o parun nisinsinyi; bẹ̃ni nwọn kò si ni ìpín mọ lailai ninu ohun gbogbo ti a nṣe labẹ oorùn (ni ayé yìí), Ohunkohun tí ọwọ́ rẹ ri ni siṣe, fi agbara rẹ ṣe e; nitori ti ko si ète, bẹ̃ni kò sí ìmọ̀, tabi ________ ni isa-òkú nibiti iwọ nrè.

   Àkíyèsí: Rárá! Bibeli yéni dáradára. Òkú kò le se ohunkohun bẹ̃ kò mọ ohun to nsẹlẹ̀ nínú ayé mọ́.
   **Orin Dafidi 115:17**
   Òkú kò yin Oluwa, ati gbogbo awọn tí o sọkalẹ̀ lọ sinu idákẹ́.
   **Orin Dafidi 6:5**
   Nítorítí kò sí irantí rẹ ninu òkú: ninu isa òkú tani yio dupẹ fun ọ?
   **Jobu 7:10**
   Ki yio pada sinu ilé rẹ̀ mọ́, bẹ̃ni ipò rẹ̀ ki yio mọ̀ ọn mọ́.
   **Isaiah 38:18**
   Nitori iboji kò le yìn ọ, ikú kò le fiyìn fun ọ: awọn ti o sọkalẹ̀ lọ sinu ihò kò le ni ìrètí otitọ rẹ.
   **Orin Dafidi 146:4**
   Ẹ̀mí rẹ̀ jade lọ, o pada si erùpẹ̀ rẹ̀ ; li ọjọ́ náà gan, ìrò inu rẹ̀ run.

3. Gẹ́gẹ́ bi ìwé Ifihan, tani o ní kọ́kọ́rọ́ ikú dání ?
   **Ifihan 1:18**
   Emi li ẹniti o mbẹ ________, tí o sì ti ________; sì kiyesi i, emi si mbẹ ________ si i títí láí, Amin; mo si ni kọ́kọ́rọ́ ikú ati ti ipò-òkú.

   Àkíyèsí: Bibeli lọ tààrà. Jesu nikan ló ní kọ́kọ́rọ́ ikú. O yẹ ki a lọ si inú ọ̀rọ̀ Rẹ̀ lati wa ìdáhùn sí ìbéèrè wa nípa ikú.

4. Bawo ni Ọlọrun ṣe da ènìyàn ni àtètèkọse?
   **Genesisi 2:7**
   OLUWA Ọlọrun si fi ________ ilẹ̀ mọ ènìyàn; o si _____ èémí _____ si ihò imú rẹ̀; ènìyàn si di alàààyè ọkàn.

   Àkíyèsí: Ohun meji lo sẹlẹ̀ ni ìgbà ti a ndá ènìyàn: (1) Ọlọrun dá ènìyàn lati inú eruku tàbí erupẹ ilẹ̀ ati pé (2) Ọlọrun mí èémí ìyè sí ihò imú rẹ̀. Ènìyàn si di alàààyè ọkàn.

5. Kíló ma nsẹlẹ̀ ni akókò ikú?
   **Oniwaasu 12:7**
   Nigbana ni ________ yio padà sí ilẹ̀ bi o ti wà rí, _______ yio sì pada tọ Ọlọrun tí o fi i funni.

   Àkíyèsí: Ohun tó ma n sẹlẹ̀ ni akókò ikú jẹ́ odi kejì ohun tí o ma nsẹlẹ̀ ni ìgbà ti a dá ènìyàn. Ara yio padà di erupẹ, ẹ̀mí tabi èémí yio sì padà sí ọdọ Ọlọrun tí o fi i funni. Bibeli fi ye wa kedere pé "ẹ̀mí" tó npadà si ọ̀dọ̀ Ọlọrun jẹ́ èémí ìyè, èyí ti Ọlọrun mí sí ihò imú ènìyàn lati ìbẹ̀rẹ̀ (Jakọbu 2:26, Jobu 27:3; Jobu 33:4). Orin Dafidi 104:29, 30 sọ wípé: "Iwọ gba ẹmi wọn, nwọn kú, nwọn si padà si erùpẹ̀ wọn. Iwọ rán ẹ̀mí (èémí) rẹ jade, a si da wọn."

6. Níbo ni awọn òkú ma nlọ bí wọn ba ti kú tán?
   **Jobu 21:32**
   Sibẹ a o sì sin i li ọ̀nà ___________ , yio si ma ṣọ́ orori òkú.
   **Johannu 5:28,29**
   Ki èyí ki o máṣe yà nyin li ẹnu; nitori pé wakati mbọ̀, ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni ___________ yio gbọ́ ohùn rẹ̀, Nwọn o si jade wá; awọn ti o ṣe rere, si ajinde iye; awọn ti o si ṣe buburu, si ajinde idajọ.

   Àkíyèsí: Awọn òkú tí ò jẹ olododo tabi alaisododo wà ninu iṣa òkú, wọn yio gbọ́ ohùn Jesu nígbàtí o ba npè wọn lati gba ìdájọ́ tabi èrè.

7. Bibeli mú ko yé wa pé Dafidi jẹ́ ẹni ìgbàlà. Njẹ́ o wà lọ́run bayi?
   **Ise Awon Aposteli 2:29**
   Ará, ẹ jẹ́ kí emi ki o sọ fun nyin gbangba niti Dafidi baba nla pé, ó _______ , a si ________ in, iboji rẹ̀ si mbẹ lọdọ wa títí o fi di oni yi.
   **Ise Awon Aposteli 2:34**
   Dafidi kò sà ________ lọ sí ọrun: ṣùgbọ́n oun tikararẹ̀ wípé, OLUWA wí fun Oluwa mi pé, Joko li ọwọ́ ọ̀tún mi.

   Àkíyèsí: Rárá! Peteru aposteli sọ gbangba pé Dafidi kú a sì sin in - kò sí li ọrun. Ni àfikún, Heberu 11:32-40 tún mú ko yé wa kedere pé gbogbo awọn olotitọ lọmọde ati àgbàlagbà ni wọn kò i ti gba èrè, dipò èyi, gbogbo wa ni yio gba éré papọ̀ (ẹsẹ 39, 40).

8. Ṣùgbọ́n ṣe kì íṣe otitọ ni wipe ẹ̀mí ki i kú ati pé ara nìkan lo ma nkú?
   **Ezekieli 18:4**
   Kiyè si i, gbogbo ọkan ni t'emi; gẹ́gẹ́ bi ọkan baba ti jẹ́ t'emi, bẹ̃ni t'emi ni ọkan ọmọ pẹ̀lú; ________ ti o ba ṣẹ̀, on o ________.
   **Jobu 4:17**
   Ẹni ________ le jẹ olododo niwaju Ọlọrun, ènìyàn ha le mọ̀ ju Ẹlẹda rẹ̀ bí?
   **1 Timoteu 6:15,16**
   Èyiti yio fi hàn ní ìgbà tirẹ, ẹniti iṣe Olùbùkún ati Alagbara náà kanṣoṣo, Ọba awọn ọba, ati ________ awọn oluwa; Ẹnikan ________ ti o ni àìkú, ti ngbé inu imọlẹ ti a kò le sunmọ, ẹniti ènìyàn kan kò rí rí ti ko si le ri: ẹniti ọla ati agbara títí lai iṣe tirẹ. Amin.

   Àkíyèsí: Ẹ̀mí ni wa, ẹ̀mí si ma nkú. Ènìyàn jẹ́ ẹni kikú. Ọlọrun nikan ni ki i kú. Ẹ́kọ́ to gba ayé pé ẹ̀mí ki i kú, kò sí ninu Bibeli. Ẹ̀kọ́ ènìyàn ni.



YOR-SP9.indd 1 5/23/13 1:49 PM

9. Ìgbà wo ni a o fun àwọn olódodo ní àìkú?

**1 Korinti 15:51-53**

Kíyèsi i, ohun ìjìnlẹ̀ ni mo sọ fun nyin; gbogbo wa kì yio sùn, ṣùgbọ́n gbogbo wa li a o ________, Lọ́gán, ni iṣẹ́ju, nigbà ________ ikẹhìn: nitori ìpè yio dún, a o si ji awọn òkú ________ li àìdíbajẹ́ a ó si pa wa lara dà, Nitori pé ara ìdibàjẹ́ yi kò le sàìgbé aidibajẹ́ wọ̀, ati ara kíkú yi ko le sàìgbé ara àìkú wọ̀.

**1 Tessalonika 4:16**

Nitori Oluwa tikararẹ yio sọkalẹ lati ọrun wa ti on ti ariwo, pẹlú ohun olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn ________ ninu Kristi ni yio si kọ ________.

Àkíyèsí:Bẹẹni, awọn olódodo yio gba àìkú ni ìgbà ajinde. Awọn ẹni buburu kò ni gba àìkú.

10. Bawo ni Bibeli ṣe nsọ̀rọ̀ lemọ́lemọ́ nípa ikú?

**Johannu 11:11,14**

Nkan wọnyi li o sọ: lẹhin eyini o si wí fun wọn pé, Lasaru ọ̀rẹ́ wa ________; ṣùgbọ́n emi nlọ ki emi kí o le ji i dide ninu orun rẹ̀, Nigbana ni Jesu wi fun wọn gbangba pé, Lasaru kú.

**Matteu 27:52**

Awọn isa òkú sì ṣí sílẹ̀; ọ̀pọ̀ òkú awọn ẹni mímọ́ ti o ti ______ si jinde.

**2 Samueli 7:12**

Nígbàtí ọjọ́ rẹ ba pé, tí ìwọ o sì _______ pẹlu awọn baba rẹ, emi o si gbé irú-ọmọ rẹ lékè lẹhin rẹ, èyí tí o ti inú rè jade wa, emi o si fi idi ijọba rẹ kalẹ.

**1 Tessalonians 4:14**

Nitori bi awa ba gbàgbọ́ pé Jesu ti kú, o sì ti jinde, gẹ́gẹ́ bẹẹni Ọlọrun yio mu awọn ti o _______ pẹlu ninu Jesu wà pẹlu ara rẹ.

Àkíyèsí: Bibeli sábà ma npé ikú ni oorun. Ikú jẹ́ ipò ti ènìyàn ki i ti mọ ohun to nṣẹlẹ̀, laarin ìṣẹ́jú marundinlogun sí ẹgbẹrun kan ọdun, wọn jọ ra. Ikú ni "oorun" ninu iboji títí di ìgbà ajinde, ti a o ji gbogbo wa dìde nipasẹ Jesu. Ẹ̀kọ́ to fihàn pé ẹ̀mí awọn òkú jẹ́ awọn angẹli ọrun tabi awọn olododo ti o ti kú ti a tún le è bá pàdé (tabi àkúdàáyà), kò ni ifẹṣẹmulẹ ninu Ìwé Mímọ́.

11. Níwọ̀n ìgbàtí awọn àjẹ́, osó ati emèrè ko le ba òkú sọ̀rọ̀, tani wọn nbá sọ̀rọ̀?

**Ifihan 16:14**

Nítorí ẹ̀mí esu ni wọn, ti nse ___________, awọn ti njade lọ sọ́dọ̀ awọn ọba gbogbo ilẹ ayé, lati gba wọn jọ sí ogun ọjọ́ nlá Ọlọrun Olodumare.

Àkíyèsí: A ma npe àwọn angẹli ọrun ní "ẹ̀mí ti njíṣẹ" (Heberu 1:14) tí wọn n ran ènìyàn lọ́wọ́ ninu ayé. Awọn angẹli ti a le jade li ọrun pẹlu Satani (Ifihan 12:7-9) náà jẹ́ ẹ̀mí - awọn ẹ̀mí to ntàn ènìyàn jẹ nípasẹ̀ iṣẹ́-iyanu (Ifihan 16:13,14). Wọn nlo "agbára gbogbo, ati àmì ati iṣẹ́-iyanu èké" (2 Tessalonika 2:9), wọn sì tún le "mú iná sọkalẹ̀ lati ọrun wá si ilẹ̀ ayé níwájú awọn ènìyàn" (Ifihan 13:13). Bí awọn ẹlẹmi èsù ba nsọ wípé awọn ni ẹmi abokusọ̀rọ̀, a ṣe wípé wọn wà lara awọn angẹli Satani to subú (Isaiah 8:19,20).

12. Kinni ìdí tí Satani fi fẹ́ ki a gbàgbọ́ wípé awọn ẹ̀mí awọn òkú wa lááyè síbẹ̀?

**Matteu 24:24,25**

Nitorí awọn èké Kristi, ati èké woli yio dide, nwọn o si fi ________ ati ohun iyanu nlá hàn; tobẹ́ẹ́ bi o le ṣe e ṣe nwọn o ________ awọn ________ paapaa, Wo o, mo wi fun nyin tẹ́lẹ̀.

Àkíyèsí: Iró tí Satani kọ́kọ́ pa fún ìran ènìyàn ni pé "Ẹnyin ki yio kú ikú kíkú kan." Genesisi 3:4. Ó fẹ́ ki gbogbo ènìyàn gbagbọ pé ẹmi awọn òkú wa lááyè, kí awọn angẹli rẹ̀ (èṣù) le dabi awọn àyànfẹ́, ati woli, ati bi i awọn olori to ti kú tí wọn si jẹ olododo, ki àwọn angẹli èṣù le dabi awọn angẹli imọlẹ (2 Korinti 11:13-15). Nitori náà, o le e tan awọn ènìyàn jẹ pẹlu milionu. Lilo ẹ̀mí èṣù wọnyii ni a npè ni "àjẹ́, oṣó, emèrè, ògbóni." Ìgbàgbọ́ ninu iwọnyi pín sí ọ̀nà meji: (1) awọn òkú wa lááyè, ati (2)wọn le lọ bá ènìyàn tabi ki eniyàn lọ ba wọn. Èyí jẹ́ ọkan lara ẹ̀kọ́ èṣù to npanirun. Síbẹ̀, gbogbo ayé lo fẹ́rẹ̀ gbà á gbọ loni. Àjẹ́ Édórì kò pe Samueli gòkè ṣùgbọ́n dí pò bẹ́ẹ̀, obinrin náà ri angẹli ẹlẹmi èṣù tí o jọ Samueli.

13. Bawo ni Satani yio se lo awọn ẹ̀mí èṣù yii tó ni ìgbà ìkẹhìn?

**Ifihan 18:23**

Ati ìmọ́lẹ̀ fitila ni ki yio sì tàn ninu rẹ mọ́ láí; a ki yio sí gbọ́ ohun ọkọ ìyàwó ati ti ìyàwó ninu rẹ̀ mọ́ lai; nítori pé awọn onisòwò rẹ li awọn ẹni nlá ayé; nitori pe nipa oṣó rẹ li a fi ________ orilẹ-èdè ________ jẹ.

**Ifihan 18:2**

O sì kígbe li ohùn rara, wípé, Babiloni nlá subú, o subú, o si di ibujoko awọn ẹ̀mí èṣù, ati ihò ________ àìmọ̀ ________, ati ilé ẹyẹ àìmọ́ gbogbo, ati ti ẹyẹ irira.

**Ifihan 12:9**

A si lé dragoni nlá náà jade, ejò lailai nì, tí a npè ni Èṣù, ati Satani, ti ntàn ________ aye jẹ, a si le e jù sí ilé ayé, a si le awọn angẹli rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.

Àkíyèsí: Pẹlu iṣẹ́ ìyanu Satani (oṣó) nipasẹ awọn angẹli ẹlẹmi èṣù, yio fẹ tan gbogbo ayé jẹ tán.

14. Báwo ni Ọlọrun se pe iṣẹ́ ìyanu to nsẹlẹ̀ nipasẹ awọn ẹ̀mí èṣù wọnyi?

**Lefitiku 20:27**

Ọkunrin pẹlu tabi obinrin tí o ní ìmọ̀ afọṣẹ, tàbí ti iṣe ________, pípa ni kí a ________ á: òkuta ni ki a fi sọ wọn pa: ẹ̀jẹ̀ wọn yio wà lori wọn.

**1 Timoteu 4:1**

Ṣùgbọ́n Ẹ̀mí ntẹnumọ ọn pé, ní ìgbà ìkẹhìn awọn miran yíò ________ ninu ________, nwọn o maa fiyesi awọn ẹ̀mì ti ntan-ni-jẹ, ati ẹ̀kọ́ awọn ẹ̀mí èṣù.

**Efesu 5:11**

Ẹ ma si ba ________ iṣẹ ________ kẹgbẹ́ pọ̀, ṣùgbọ́n, ẹ kúkú maa ba wọn wí.

**Galatia 5:19-21**

Njẹ awọn iṣẹ ti ara farahàn, ti ise wọnyi; pansaga, àgbèrè, ìwà-èérí, wọ̀bìà, Ìbọ̀rìsà, ________, irira, ìjà, ìlara, ìbínú, aṣọ̀, ìṣọ̀tẹ̀, adamọ̀, Arankàn, ìpànìyàn, imọtipara, iréde-òru, ati irú wọnni: awọn ohun ti mo nwí fun nyin tẹ́lẹ̀, gẹ́gẹ́ bi mo ti wi fun nyin tẹ́lẹ̀ rí pé, awọn ti nṣe nkan bawọnni kì yio jogún ijọba Ọlọrun.

**Ifihan 21:8**

Ṣùgbọ́n awọn ojo, ati alaigbagbọ́, ati ẹni irira, ati apànìyàn, ati àgbèrè, ati ________, ati abọrìṣà, ati awọn èké gbogbo, ni yio ní ipa ti wọn ninu adágún ti nfi iná sulfuru jò: eyi ti iṣe ikú kejì.

Àkíyèsí: Ní ìgbà ayé Mose, Ọlọrun paṣẹ pé gbogbo awọn oṣó ni ki wọn ko pa. Loni Ọlọrun n sọ wípé iṣẹ ara ni oṣó, awọn eniyàn ti a o parun. Ọlọrun kìlọ̀ pé bi o ba darapọ̀ mọ oṣó wà á kuro ninu ìgbàgbọ́, Ọlọrun sì sọ fun wa wípé awọn oṣó yio kú ninu ikú kejì ninu adagún iná.

15. Kinni agbara ologo tí Ọlọrun ma n fún awọn eniyàn Rẹ̀?

**Fillipi 3:10**

Kí emi kí o le mọ̀ ọn, ati agbara ________ rẹ̀, ati alabapin ninu ìyà rẹ̀, nígbàtí mo ba faramọ́ ikú rẹ̀.

Àkíyèsí: Jesu fun wa ni agbara lati ma a gbé nínú ayè nipasẹ aṣẹ to ji I dide kúrò ninu òkú. Igbadùn nlá! Bawo ni a o ṣe kùnnà agbara iyanu ti o fi fun wa - lai sí idíyele kankan? Nitori pé Jesu fẹran wa, o fi sùúrù gbà wá níyànjú pé kí a yàgò fún agbara iyanu ti awọn angẹli ẹ̀mí èṣù, o wa fun wa ni iyanu atọrunwá ti a nílò, tí yio pèsè wa fún Ìjọba Rẹ̀ (Fillipi 1:6).

# Èsì Rẹ

Mọ èyí dájú wípé Ọlọrun ni o n ṣe akoso gbogbo ayé, njẹ iwọ náà fẹ́ ki Ọlọrun gba gbogbo akoso ayé rẹ bí?

ÌDÁHÙN: _______________

# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ọ̀rọ̀ afikun lati tun mu wa kẹkọ síwájú.

## Olè ori Àgbélèbú

Sé Jesu se ileri fún olè orí àgbélèbú pé lójú kanna yio ni oore-ọ̀fẹ́ lati dé ọrun nigbati O sọ wípé, "Loni iwọ o wà pẹlu mi ni paradise"? Itumọ̀ ọ̀rọ̀ Kristi ninu ìwe Luku ori kẹtalelogun ẹṣẹ ikẹtalelogoji (23:43) n sọ pẹlu iwe mímọ́ yii lati dahun ibeere pàtàkì yìí pé: Sé Jesu funrara Rẹ̀ lọ si ọrun ni ọjọ́ náà?

Ni ọjọ́ ajinde, nigbati Jesu ba Maria pàdé ni iboji, ọ̀rọ̀ Rẹ̀ ni: "Máṣe fi ọwọ́ kàn mí, nitori ti emi kò ti igòkè lọ sọdọ Baba mi." Johannu 20:17. Kò se e ṣe wípé Jesu lọ sí paradise ni ọjọ́ Ẹtì (Friday), bi o ba jẹ bẹ́ẹ̀, kò le e gòkè lọ sí ọdọ Baba ni ọjọ́ Àìkú (Sunday)!

Ki wa ni ìdí ti Jesu fi wipe. "Loni iwọ o wà pẹlu mi ni paradise"? Isoro tí a n dojú kọ lórí ọ̀rọ̀ yìí, yíò di ohun ìgbàgbé nígbà ti a ba ri ojulowo bi a se kọ ọ silẹ ni èdè Giriki. Awọn àmì idanudúro díẹ̀ ati awọn àmì mìràn ti a n lò lati fi kun ọ̀rọ̀ inu ìwé mímọ́ nipaṣẹ awọn atúmọ̀ Bibeli ni wọn n lò funrara wọn. Yálà o gbagbọ tabi o kò gbà mí gbọ́, àmì idanuduro díẹ̀ le yi gbogbo itumọ̀ gbolohun padà! Ọ̀rọ̀ Oluwa ninu iwe Luku 23:43 yẹ ko jẹ́: "Lootọ ni mo wí fun ọ loni, Iwọ yio pẹlu mi ni paradise." Èyí jẹ ohun ti Jesu n sọ dájú. Loni, nigbàti gbogbo ènìyàn dabi pe wọn ti sọnu, loni ti Mi o dabi Ọba tabi Oluwa, lẹhin ti awọn ọmọ ẹyin mi ti sa lọ; loni, tí o jẹ wípé a kan ọwọ́ mi mọ agbelebu, Mo tun le gbàlà!

Nitori náà, lọjọ kan olè náà yio di ẹni ajinde yio sì wà pẹlu Jesu ni paradise ati awọn ti wọn gba Jesu ni Oluwa ati Olugbala wọn.

## Kinni ọ̀rọ̀ yii "Ẹ̀mí" ati "Èémí" tumọ̀ sí ninu Bibeli?

Jobu 27:3 sọ wipe ènìyàn jẹ "Ẹ̀mí" ati "Èémí" jẹ́ bakanna. Jobu tún tẹṣiwájú lati fi ye wa pé ẹ̀mí ati èémí wà ninu ihò imú. Rántí pé Ọlọrun fi "èémí" sí ihò imú Adamu nígbà ti a da (Genesisi 2:7). Nitori náà ẹ̀mí ti o ma n pada si ọdọ Ọlọrun nigbati ẹnikan ba ku ni èémí ìyè - ti ki i se ohun tí ko ni ara. Kò si ibi ti a ti wipe ohun ti ko ni ara padà si ọdọ Ọlọrun lẹhin ikú ninu Bibeli.

## Nibo ni "Ẹ̀mí" ma n lọ nigbati ènìyàn ba ti kú ?

Ni ìbẹ̀rẹ̀, ohun meji ni o para pọ̀ ti wọn di ẹ̀mí - ara ati èémí. Ki awọn ohun meji yii to parapọ̀, kò sí ohun to n jẹ́ ẹ̀mí. Ni ìgbà ikú, awọn ohun meji yii ma n pin yà. Ara ma n padà si inú erupẹ̀, ẹ̀mí yio sì padà sí ọdọ Ọlọrun. Ẹ̀mí ko lọ ibi kankan; yio kan dẹku lati ma a wà.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678





YOR-SP9.indd 2 5/23/13 1:49 PM